# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

NO 870 SATURDAY DECEMBER 12, 1964 (2D

## Enia Mẹta Fara Pa Ninu Ija Ẹgbẹ Oṣelu

ISẸYIN:- Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹkanla oṣu yi ni irohin de ọwọ wa pe awọn enia mẹta ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan fi ara igbọgbẹ nibi ija nla kan ti o ṣẹlẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu eyi ti o ṣẹlẹ ni ilu Iṣẹyin ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejọ oṣu yi, awọn enia to fi ara gbọgbẹ na ni nwọn jẹ oniṣowo ni ilu Iṣẹyin awọn na ni Ganiyu Iṣhọla, Bandele Iṣhọla ati Salawu Gbọlaga eyi ti irohin fi ye wa pe nwọn ti ko wọn lọ si ile Iwosan ti ilu Ọyọ fun itọju,

Irohin na fi ye wa pe ohun to fa ija na ni pe awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan wọ ile Ọgbẹni Alabi Yerokun ti o jẹ Minista kekere ni ile iṣẹ Minista Alamojuto eto irohin fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria eyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu na fi ye awọn enia na pe ki nwọn kegbe orukọ Olori ẹgbẹ Oṣelu kan tabi ki nwọn kegbe orukọ to jẹmọ ti ẹgbẹ Oṣelu.

Ṣugbọn nigbati awọn enia na kọ delẹ lati kegbe orukọ na ni ija ba bẹrẹ eyi to fi jẹ pe nwọn bẹrẹ si ni fi afoku igo, ada ati awọn okuta fi ba ara wọn ja eyi ti enia mẹta si fi ara gbọgbẹ nibẹ.

### "OLUWA RERE GBA NAIJIRIA KURO NINU IWA OJUKOKORO"

# DOKITA AZIKIWE KILỌ FUN AWỌN OLORI ẸGBẸ OSELU !

**EKO:- Ni ọjọBọ ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni Alakoso ilẹ Naijiria Dọkita Nnamdi Azikiwe ti kesi awọn Olori ilẹ Naijiria ati awọn olori ẹgbẹ oṣelu lori eto ipolowo ibo fun imura silẹ fun idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria to mbọ yi eleyi ni awọn ọrọ ti Alakoso ilẹ Naijiria Ọlọla Dọkita Azikiwe fi kesi awọn Olori ilẹ Naijiria.**

Ẹnyin enia mi lọkunrin ati lobinrin mo si ti tu ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka lori eto ofin ilẹ Naijiria. Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati awọn Minista apapọ Ijọba ilẹ Naijiria yio ti wa gẹgẹbi awọn igbimọ afunsho fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria.

Dọkita Azikiwe si fi ye awọn olori ilẹ Naijiria pe on fi ọrọ on na kesi awọn olori ilẹ Naijiria ati pe nkan ba ṣẹlẹ si orilẹ ede ilẹ Naijiria loni yio si kan gbogbo awọn olori ilẹ Naijiria na larin ati awọn enia to wa lẹhin wọn.

Dokita Azikiwe si sọ pe on fẹ ki awọn olori ilẹ Naijiria awọn Gomina, awọn olotu Ijọba ipinlẹ, Alakoso apapọ Ijọba, awọn oloye ni ilẹ Naijiria, awọn olori ẹgbẹ Oṣelu ilẹ Naijiria ati awọn Olorini gbogbo ọna orisirisi ni orilẹ Naijiria gẹgẹbi mo ti ṣe eto ti mo ṣe ibura lati di abo bo ofin ilẹ Naijiria iṣe mi ni gẹgẹbi Alakoso ilẹ Naijiria lati le da abo bo gbogbo awọn eto ti o ba jẹ ti ọmọ ilẹ Naijiria lọna ti eto idibo to mbọ yio si lọ ni ọna eto larin awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu.

Ọlọla Dọkita Azikiwe sọ pe inu on ko dun si iru awọn nkan ṣo n tẹlẹ larin ọn



**Dọkita Nnamidi Azikiwe**

ọmọ ẹgbẹ Oṣelu to wa ni ilẹ Naijiria ati pe on i ti nwọn ngba ṣe eto ibo ko si ba oju mu rara.

Dokita Azikiwe tun ṣe alaye pe opolopọ awọn ẹgbẹ Oṣelu ni awọn ẹgbẹ Oṣelu ti nwọn jẹ Alatako si ẹgbẹ wọn ko si fun ni aye lati fi ye awọn enia ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ wọn lori nkan ti ẹgbẹ wọn duro fun ati ohun ti ẹgbẹ wọn yio ṣe lẹhin ti nwọn ba wọle.

Alakoso ilẹ Naijiria na tun sọ pe ọkẹ aimọye iwe ati waya ni on ti ri gba lori iwa ti awọn ẹgbẹ Oṣelu kan nhu si awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu ti o jẹ Alatako wọn eyi ti Dọkita Azikiwe tun ṣe alaye pe ninu iwe na ni nwọn ti nsọ fun on pe ki on ṣe ọna ati pe ki on lo ipo rere lati le jẹ ki eto dibo to mbọ yi wa lọna ẹtọ ati pe ki nwọn si tele eto ọna ofin lori eto idibo na.

Dokita Azikuwe tun ṣe alaye pe ọkẹ aimọye iwe lo tun ri gba lori iwa to jẹ pe o buru ati eyi to jẹ pe itiju lo jẹ fun ilẹ tun gegebi Naijiria lati mọ ri pe awọn ẹgbẹ oṣelu kan to wa ni alakoso Ijọba tabi pe ti nwọn ni agbara ni ipinlẹ kan fi iya ma nje awọn ẹgbẹ oṣelu ti o jẹ Alatako si wọn lori pe ki nwọn ma jn wọn s'ẹwọn lori aimọdi tabi pe ki nwọn fi ọlọpa ma mu wọn ki nwọn si ma ti nwọn mọle lai gba iduro wọn eyi ti o jẹ pe o lodi si eto ofin ilẹ Naijiria.

Dọkita Azikiwe ṣe alaye pe ti iru iwa bayi ba jẹ ojitọ o ni eleyi mu abuku ba ilẹ Naijiria.

Dọkita Azikiwe ṣe alaye pe awọn ẹgbẹ Oselu to ba wa ni ako so Ijọba si jẹ awọn ẹgbẹ Oṣelu ti awọn ilẹ Naijiria fẹ o ni eleyi o si mu ki nwọn ma lo agbara lati ma lọ awọn Ọlọpa Ijọba bile tabi awọn ọna miran to io ia owo- to wọn l ti fi iyẹn na gbe og n ti awọn ẹgbẹ Oṣelu ti nwọn e Alatako si wọn. O ni eleyi si wa lati le jẹ ki awọn enia mọ iru oaun ti nwọn ṣe fun awọn enia ti o dibo fun won wole lasiko na ati pe ohun ti awon enia to dibo fun wọn na yio tele ni yẹn to ba jẹ rere tabi tabi buburu ni nwon ṣe

Dokita Azikiwe so pe ti o

Wo Oju Ewe Kẹfa

## AKIYESI PATAKI

Idije Orilẹ Pọnun marun yio jade ninu Iwe-Irohin Imọlẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi

Kini o ngbare wa Owo ti o fẹ fi ṣe Ọdun yi si? Maṣe ṣe wahala kakiri mọ, nigbati Pọnun marun le jẹ tirẹ lofe ni ọjọ kanṣoṣo bi o ba le ka Iwe Irohin Imọlẹ.

Ah! Ẹbun nla ni eleyi fun gbogbo ẹnyin Onkawe wa

Maṣe alaiko ra Iwe Irohin Imọle ni ọtunla.

OLOTU

# ORE WO NI DẸMỌ ṢE SI ILE — IFẸ ?

## Lati Ọwọ ẸRUKOBODO

### AKIIṢODI SI ONI

ỌRỌ AGBA:— Mari wo ọpẹ ti o ba fi igbago s'ẹsin, on na mbọ wa di ohun a gbẹ le he; Ki owe yi jẹ ti ọmọ Adimula, to sọ sinu Irohin Imọlẹ laipẹ ọjọ yi wipe Ki yio si ijoko Dẹmọ kan ni Ile Ifẹ. O ti pẹ ti a ti ngbọ lẹnu awọn baba wa wipe:— A ki isodi si Ọni itumọ eyi ni wipe, ẹnikan ki ihuwa to lodi, tabi, huwa abuku si Ọni.

Ọga ati ọmọ iṣẹ ẹgbẹ Dọmọnu paapa ti mo lọkan ara wọn ati ninu iṣesi wọn si ọmọ Ile Ifẹ wipe, bi nwọn nfon Ibo kiri ilu ẹ g b ẹ Dọmọ n u ko le ri ẹyọ ibo kan ti yatọ si ti iyawo pẹlu awọn ọmọ wọn ninu apoti Ibo ti nwọn ba gbe kalẹ si Ile Ifẹ ninu Ibo ti ọjọ rẹ kusi dẹdẹ yi.

Kini ohun to le mu inu ọmọ Ile Ifẹ dun de bi nwọn yio fi gba ẹgbẹ Dọmọnu la ye ni Ile Ifẹ? Lati ọjọ ti aiye ti di aiye awọn ẹgbẹ Oselu gẹgẹbi a ṣ a awọn Oyinbo koiti si ẹgbẹ Oṣelu kan to gboju gbaiya huwa abuku si Ọni Ile Ifẹ ri kosi si ojulowo ọmọ Ile Ifẹ kan ti yio ranti bi Ọba Alaiyelu wa ADESỌJI ADERẸMI ỌNI ILE I F Ẹ t i iṣe baba gbogbo ọba i l ẹ Yoruba tiṣe foru boju ṣa kuro lori ipo Gomina ti ẹgbẹ Afẹnifere fi da lọla ti yio ni inu didun si ẹgbẹ ti Dọmọnu

Ojulowo ọmọ Ile-Ifẹ wo ni yio ranti imọran ika ti awọn Igbimọ alabẹ ṣekele to mbẹ ni abẹ opo A ṣ i a ẹgbẹ Dẹmọnu ni Ile-Ifẹ da si Ọba Aderẹmi ninu ipin-



ỌBA ADESỌJI ADERẸMI
Ọni Ti Ifẹ



OLOYE AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

nu ti nwọn ṣe lati le gbe Ọni Ile-Ifẹ lọ fun yanmuyanmu jẹ leti okun Agbadarigi, ti inu rẹ yio dun lati ṣe ẹgbẹ Dẹmọnu ?

OJULOWO YORUBA

Bi a ba nsọrọ Yoruba Ile Ifẹ ni Yoru a ti ṣe iwa ojulowo Yoruba ra ni wọn si nhu pẹlu ẹgbẹ Dẹmọnu ti opolopọ ti leri wipe ti ẹgbẹ Dẹmọnu ni nwon nṣe Ifẹ ko ṣe ẹ g b ẹ Dọmọnu rara. Ki ẹ to mo wipe I f e ko fẹ odi jo idibo Kosi ojulowo ọmọ Ifẹ kan ti a bii nile lona ni igboro Ile-Ife ti yio se wipe tife-tife tabi tayo tayo ni on fi ba won ṣe ẹgbẹ Domọnu biko ṣe wipe nwọn ṣe e ni a ṣe ni a ṣ ri ilu gbe ni ati pe opolopo won lo ṣe ẹ ki nwon o maṣe di ẹ l ẹ w o n osan gangan.

Nigbati inu ore wo ni ẹgbẹ Domọnu ṣe si igboro ẹle Ifẹ lati ojo ti nwọn ti lẹrẹ si ṣe ijoba tipa-tipa wọn yi ti o le mu inu omo Ifẹ dun debiti nwọn yio gba ẹgbẹ Dọmọnu laye ?

Ti ọmọ wọn (ọmọ Omiṣade Ogbolu) ti a bi nile lọna to mbẹ lọgba ẹwọn kọ ni ko to ro fun wọn ti nwọn yio fi ni inu diun si ẹgbẹ Dọmọnu? tabi, tiaimọye ọmọ wọn ti awọn janduku ẹgbẹ Dọmọnu ti sọ di alamodi nipa alubolẹ, tabi, eyi ti o tit ori wahala wọn sa fi ọmọ ati iyawo rẹ silẹ jade kuro ninu i l u

Gẹgẹbi ọrọ ọmọ Adimula



OLOYE FANI-KAYỌDE
Igbakeji Olori Ẹgbẹ Dẹmọ



Alagba ẸRUKOBODO

emi na ri i daju gbangba wipe, bi nwọn ba nfi ibo ṣe saara kiri ilu, ẹ g b ẹ Dọmọnu ko le ri eyọ Ibo kan ninu apoti Ibo ti nwọn ba gbe silẹ larin ilu Ile Ifẹ nitoripe, nwọn ti huwa to lodi si ofin iṣedale ti Odudu wa fi lelẹ ni Ile Ifẹ.

Bi araiye ba n f ẹ dibo na fun ẹgbẹ Dọmọnu wọle oduduwa; Ọ b a Atẹrẹrẹ kaiye; Esi idalẹ Ifẹ, ti o ni ilẹ rẹ kọni jẹ: nitori pe, „A kigba akaga lọwọ Akiti Onikan ki igba i l e baba ọmọ lọwọ ọmọ (Eewọ Orira

(OLOMI IGO NLA NI)
BERE EGBOGI AJỌ WỌN NPENI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba laila k wọn Orişiriş robirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to ada tiawọn agbalagba aiye atijọ mu ati wipe ko si ohuukul ale fi iwe egbogi yi bi otutu iko iba, orẹrẹ luoduku onirbameji t i aiperi n yọ enia lẹnu y ala Ọmbe tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oa ti ta die sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọn eti riro tabi se iwosan iyọnnu apo ile ito egbogi oju didun tabi ni ona-ọfun didun, ati orişirişi omiran pẹlu wọn mbẹ n ṣọbu awọn:-

NIGERIA - MEDICINE STORE
4, Tinubu Sqare Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
Palm church Street, Lagos

# IWE SI OLOTU

## A Dupẹ Lọwo Azikiwe

Olotu, jọwọ gba mi ni aye rampẹ ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati kesi ọlọla wa baba wa Dokita Nnamidi Azikwe lori iṣẹ nla ti o ṣe lati tu ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka eyi ti awa adibo nreti rẹ lati ọjọ yi wa.



Dọkita Azikiwe

Nisisiyi inu wa si dun pe laisi nkankan a ni lati dibo ni ọgbọnjọ oṣu yi ati pe eleyi si da wa loju pe ẹgbẹ UPGA ni yio bori ibo.

Mo tun kesi awọn ọmọ iya mi ẹlegbẹ mi ati ẹgbọn mi ti nwọn jẹ ọmọ ilẹ Yoruba lati ṣe irauti olore ki a le fi ibo wa gbe olore wa baba Ọbafemi Awolọwọ kuro l gba ẹwọn o di owo nyin o. Olotn mo dupẹ pupọ fun aye tl ẹ gba mi.

Emi ni
Dekọya Ajayi
Ile-Ifẹ

## Ẹnyin Ọmo Igbomina Ọ Di Ọwo Nyin

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu Iwe nyin Oloyin mọmọ ti o ti b Akara gbi-igbona lati kesi awọn ọmọ Igbomina lati mọ ohun ti nwọn nṣe yẹn ko ti dara to.

Ojojumọ ni mo nka Iwe Irohin Imọlẹ pe apa kan ninu awọn ọmọ Igbomina nṣe ẹgbẹ Dẹmọ apa kan nṣe UPGA eyi ko dara to nṣe ni mo fẹ ki ẹ para nyin pọ di ọkan ki ẹ dibo fun ẹgbẹ ti o nkore wọ ilu ẹgbẹ na ni ẹgbẹ ilosiwaju ilẹ Naijiria ẹgbẹ UPGA.

Ti ẹ ba le ṣe eyi yio mọ ni ninu ẹnyin l ni ẹnyin lana bi ẹkun apa ọkọ jẹ, o baiye jẹ ko fi idi ọran ọrọ na toto o ṣe bi owe ki e ro ki eto ṣe o. Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni Rafiu Abati
Eko

## Ku Inawo

Olotu inu mi yio dun pupọ bi ẹ bale gbami laye ranpẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ yoruba Oloyinmọmọ lati ki Baba wa Salami Lawal ku inawo ile re to si ni pindoro ni ọjọ Sunday ọjọ kẹfa oṣu yi nkan bi ago mẹ fa owurọ ọjọ na ni ẹsẹ gbogbo awọn ọmọlẹbi ọrẹ aburo ati awọn alaba sẹ yẹ ti pe soṣei ti ila kosi goeji Baba wa na Salami Lawal si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn enia lọrun lọjọ Ẹgan ni hẹ afi ẹni ti ko ba de adugbo bẹ to le sọ pe ebi npa on lọjọ na ki Olọrun Ọbajẹki ire rẹ ka i ẹni kọkanwa o amin aṣe eleyi ni die ninu orukọ awọn enia to wa si bi Isile na Sanusi babaraimi yusufu ayan uiyi Alhaji Babaraimi Aderu bababelau Salami akọwe Ọmọniyi A. Adeẹye ati Alhaji BabaIyabọ ki Ọlọrun alanu fi ire iru rẹ kari gbogbo wa o amin-aṣe olotu mo dupẹ aye ti ẹ gbami ọkọ ọba koni sa yin lẹsẹ o amiaaṣẹ.

Emi ni
Alhaji Abdul Karimu
ILU-ỌLA

## Ijoba Domonu Lo Abuṣe - Buṣe

Olotu, ẹgba mi laye ninu iwe Irohin nyin lati ki awọn enia ipinlẹ Iwọ - Orun Naijiria ku ewu ewu ina ki ipa awodi, awodi ẹ ku ewu" Ẹ ku amoribo ninu ipaiya airiṣe ṣe ati Aita ọja.

Ọjo kan ni ilẹ nmo lẹhin Ọkunrin Ile ojo kẹjọ oṣu December 1964 mọ lẹhin ẹgbẹ Domọnu, abuṣe - buṣe Ijọba Aktntọla lọ tete-tete. O darinnako, o daju ta ala, o tun d'ko alawo, Al o rami - rami ni a nri ẹnikan ki iri abọ rẹ nọ (Ewọ Oriṣa.)

Ki a to rinna pade Ijọba Akintọla, o tun di ọ'ọ ajinde nibiti ẹgbẹ Dọmọnu yio ti ma wa jihin iṣẹ rẹ nlwaju Oluwa.

Olotu, ẹ ku iṣẹ o. Ajinde ara yio ma jẹ o.

Kunle Lawoyin
Ibadan

## Ẹ Ma a Ka Iwe Irohin Imolẹ Lojojumo Fun Eto Ipolowo Ibo

## Salami Lawal Ẹ


**Ipolowo Ọja Rẹ Ko Ti Yege**
*Nitoripe*
O KO TI POLOWO ỌJA RẸ
SINU
**IROHIN IMỌLẸ**
T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
ADVERTISMENT MANAGER
**IROHIN IMỌLE**
16, Bamgboṣe Street Phone 21985



**Aiye Toto Afrcan Heaing Home**

Bi ogun itaia Ti o daju Ti a ṣe ni Turari pẹlu ndera. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Iroh n ko o afojuba oriṣiriṣi aruu ati ilọsiwaju t ẹnu iṣẹ pẹlu ẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ wa

Office
7, Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA **"DYNAMIREN"** TỌNIK

ALE-BI-ALE Egbogi Toniki Jamanu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹ ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ko ba ṣiṣẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun o si de adorin tabi jubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, eran ara re tio ti hunjọ vio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyẹn bẹ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu:

NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.

ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

# Ye Irawo Re Wo

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Iwo yio gbo irohin agbayanu kan loni arare siro wo nigbati oba ri eni atijo kan ti yio tunbo jeki ise re nilosiwaju fasji ale oni yio sojo fun o

PISCES (Feb 21-Mar 20) Bi oba se suru die iwo yio bori adanwo ti wa fun o nisiyi Pa gbogbo ibi ti a mole ti iwo tikoni fi si ejo da

ARIES (Mar 21 April 20) Ibiru ati oro tiko to i kan le mu o de ipo ti iwo fi ja Sora re nipa eyi Mase fi oka si aladugbo re yio ma hu lati muo bi u nipa be ewu nla kan yio rekoja lori re

TAURUS (April 21 May 20) Aiya fifo nipa ibatan re kan tio saisan mi se beru ami di na k buru to ev ti o lefeni laya bikoba d olo u lori re segun reiwo yisigbagba

GEMINI (May 21-June 21) Ij repete kan tibesile la rin ile re osiye i omo ohun tio ese nitori oro na yio di koko seni ki wa on tija n yio fi pari lar n won

CANCER (June 22-July 22) Asise kan yio wa nnu ohun tio gba lero se atunye wo re kio situ ibiti o wa se bio b le atunse b y ohun gbogbo yio ma lo letoleto

LEO (July 23-Aug 23) Ise re yio ma lo gere se ipinu loni lati ja o kuro ninu iri gba aiye k ri Alafia yio wa pelu re ni igba ti gbogbo idamu re yio pari

VIRGO (Aug 24-Sept 23) Odara kio jagbon die nipa biba awon ti n rin soro tabi io nfi oro lo Bio ba se agidi yio gbe o lu ij gbon

LIBRA (Sept 24-Oct 93) Odara kio fi nkan re dani yan iru ise tio fe lati se iwo yio nilosi aju kiakia bi a ti nsa beni kio si mura bibeko kio maba padanu

SCORPIO Oct 24 Nov Enikan yio wape o si ode ni ale iwo yio gbadun ijade na Iwo yio sije ere ule sugbon Base pe kio bale tete simi

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Sora lati jeran tu tu pupo nitori iwo yio wo ise re pupo kosi ni si ija larin iwo pelu iyawo re

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Iwo o segun gbogbo ohun tio ndao lamu yio folo

# E Jeki A Lepa Ododo

Lati igbati ipolowo ibo didi si ile Igbimo Apapo ti bere a ti nte eti wa si'e gbo ohun ti gbogbo enia nwi lotun ati losi, beni t bi beko lorisirisi.

Sugbon eyiti o je pataki ti ko ye ki a ma gbo lati enu olori Egbe ni eyiti a ngbo lati enu olori Egbe Demo ey ti o nso wipe Egbe Afenifere ko se eto Ijoba Iwo Orun d ra nigbati awon wa nile. Nje mo bi gbogbo eyi onkawe wa lere pe ipo ati ye w ni olori Egbe Demo wa nigbana? kise Igbakeji olori Egbe Afenifere ni o nse ni gbara bi, tabi gbogbo ofiin ati eto ha sese lehin re bi?

Nitorina io wun wa pupo lati fi ye i loye S. L Akintola pe ase gbogbo wa ni ope ati ogbeni ti Ija ba de ti orin si di owe o ye ki mo bi o ti to ati bi o ti ye ki a korin owe gbogbo awon ti o wa loko ti o nko won kiri ti o si p ro funfun fun wipe egbe tire ti setan lati tun Ijoba Iwo Orun se ju ti igbati Oloye Awolowo nse lo e se ti o ko se so ilu gbadun ati Agbe pe re titi de Mushin de iiu Oyingbo ninu ipolowo ibo re si Ikereku ni Agbegbe Abeokuta nko ti sope Iro funfun won ti nwon sope owo ko si ni Iwo Orun mo nipa ise egbegberun aimoye o o i o nse ni apo isura Ijoba Iwo eyiti egbe Demo nse Akoso leri re ni s siyi.

Winfred Adenij[i]
Lagos

# KERE O! Akiyesi Pataki

## Antoin Tablets ! Antoin Tablets !

Enyin Abiyamo lokunrin ati lobinrin, Mo ba yin o E ku afojuba egbogi pataki ti a se iwadi re l. ti wo awon Ojogbon Onisegun (Specialist) Ilu Oyinbo Fun awon ajakale arun wonyi:—

IGBONA:- Eyi je Arun ti o sopo nisisiyi papa jul arun awon Omode ati Agbalagba.

ORI FIFO TULU LUKULUKU OTUTU IGBA AIYA ARA RIRO ati OTUTU OREREN pelu AKO-KORO Jowo danwo ajebidan ni ogur yi. Iri hin ko afojuba Bere iwe ti e o fi l lowo eniti o ba ta Egbog n fun nyin: O daju han u . E o ri se re lehi is ju medogun ti e lo. bere lowo On segun dugbo re.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES

26, Bishop Street Phone;- 23745.

LAGOS

# Bo Lowo Oso Ati Aje

we egbogi Ajebidan 25/- mejila £2
we Ilana Ifa Iyanrin tite ati etutumet pelu iwe san 20/-22/-ejila £2 5/
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari isegun Aje, Oso ati awon aba nije O wa fun itaja pelu akala Pangolo 10/6- paketi 2- Ki se ti enu fifo i o o ri ninu awon oja yi aabo ti o nipon ni ile a e ni yio wa lori re ati awon ebi re

Fi owo ranse si

J. O. SHOYINKA
11, Alaba Street
Oduabore Mushin.

## Gbanjo ! Gbanjo

F N ODUN KERESIMESI

Eyi ni lati fi kede fun awon onibara wa pe Oja gbanjo wa bere lati oni lo titi di 30/11/64. Tete ra tire E o to kase nile

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wo Boosi Mushin, soka'e ni Atewolara Bus Stop ! Bere ladipo Street ti o ba rin titi Ladipo, bere ILE IWE ODU - ABORE. Ti o ba de ibe tan, wa be re Nomba 5, Alaba Stree Mushin, ile ise wa di jukoti ODUS SURF"

AWON OJA WA

Oluborí Egbogi Ajebidan 40s di 30s Iwe E bogi Ajebidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Arun 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin tite ati etu sise 20s di 17 Iwe Afose Isedale Yoruba ati Psalmu Ajebidan 3/6 di 2s 6d Tura i Isegun Aje 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo niti oke yi Turari ti o wa ninu paketi je 2s 6d pere Iwe Itumo Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akonni lesin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book di 1s 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Forms
Certificate of Apprenticeship (meta) 17/6 di 10/6d

OJA TITUN TI A SESE RI GBA

Abela mimo fun adura tete Idakoju (ti sinsi awo p lu Turari.

Abela mimo fun itaja (Kowo wole pelu Turari 20/-
" " , Isegun Aje pelu Turari 20/-
Lofinda tabi Ororo ipara fun itaja, Isegun Aje ati arisiki 30/- Igo kan

Fi owo ranse tabi ki o wa ra ni odo:—

J. O. Shoyinka
5. Alaba Street,
MUSHIN

# YẸYẸNATU

## ONIYẸYE EKO

Yẹyẹnatu:- Kutakuta p i n tabi ko pin?
Olotu:- Okuta wo ni o pin?
Yẹyẹnatu:- Tabi ẹ ko tilẹ gbọ Yoruba
Olotu:- Emi yẹnara Ọrọ ni
Yẹyẹnatu:- Ṣebi ẹ ni Ọṣun ni ẹ ti wa?
Olotu:- Nigbana nkọ?
Yẹyẹnatu:- Nigbana wa o ni ki oma a ki nyin
Olotu:- Ani ṣe, iyẹn lo ni ki o ma a pin okuta kiri
Yẹyẹnatu:- Mo ni kutakuta pin?

Olotu:- Kutakuta tani?
Yẹyẹnatu:- Kutakuta awọn ọrẹ nyin ni.
Olotu:- Awọn ọrẹ mi wo?
Yẹyẹnatu:- Ṣe lati ọjọ yi nwọn ko da ile Igbimọ nla Eko ru, njẹ nisisiyi nkọ gbo ko ha di ọkan?

Olotu:- Lootọ ni.
Yẹyẹnatu:- Awa ki i tilẹ ṣe ẹgbẹ wọn nisisiyi.
Olotu:- Ko sirọ nibẹ.
Yẹyẹnatu:- Nitoripe ẹni ba le dọbalẹ fun mi ni aṣo dibo fun.
Olotu:- Ha, N. N. D.P. le dọbalẹ.

Yẹyẹntu:- Otitọ ni nitori ko si ẹniti nwọn ko le dọbalẹ fun tabi?
Olotu:- Nko mọ iyen
Yẹyẹnatu :- Aanu ẹnyin Yoruba lo nṣe mi Nisisiyi atamọ bi awọn ba ti fun nyin lomo
Olotu:- Bi o ba se iwọ nkọ
Yẹyẹnatu:- Ngo gba owo ngo si wipe ọwọ ni ẹ ko rinu.
Olotu:- Iyẹn ni pe iwọ na yio ma a tan wọn jẹ
Yẹyẹnatu:- Hẹ ilẹkufẹ lo pọ l rin gbogbo wa kẹ, emi nikan kọ
Olotu:- Iwọ nikan ko ni ntan enia jẹ?

Yẹyẹnatu:- Emi na nikan kọ lo nṣe ihin ṣe ohun
Olotu:- Tani ẹnikeji rẹ?
Yẹyẹnatu:- Ẹnikeji ti emi ba aipi lati se ni inunibini on na ni ẹnike ji mi
Olotu:- Inunibini
Yẹyẹnatu:- Bẹẹni ti Yoruba ri Ibo dide njo fun UPGA ki Awolowọ le pada sile Akintola ọmọ Yoruba nba UP GA ja Benson Ijẹbu binu kuro ninu UPGA, o maṣe o
Olotu:— Sebi KAYỌDE. ọmọ ẹgbẹ N.N.D.P ni bi awọn ba wọle awọn yio mu Awolọwọ jade
Yẹyẹnatu:- Akintọla ni isọ kusọ ni o nsọ o ni ni gbati awọn ba wọle tan ni awọn yio ṣẹṣẹ wa joko ro o bi awọn ba mu u kuro lẹwọn bi awọn ko nimu kuro

Olotu:- O ni awọn ọba ni yio fi ogege le e
Yẹyẹnatu:- Ṣe awọn Ọba to ti sọdi agutan ti o si nṣe oluṣọ wọn.
Olotu:- O ko le sọ bẹ o
Yẹyẹnatu:- Ṣebi ijeelo ni Akintọla rin Ọba Ilaro fin ti inu bi gbogbo ọmọ Ilaro Ṣebi ẹbun ti Ọba fun Akintọla la pẹ yi ni pe o fi joye
Olotu;- Lootọ ni o joye ni Ilaro
Yẹyẹnatu:- N ẹ ẹ mọ idi Oye yen?

Olotu:- Nigbati o yọ ninu paper pe iyawo Awo lọwọ lọ si Ilaro awọn ẹgbẹ Dẹmọ ko jẹ ki o ri ibi ṣe pade i u u NNDP dun ṣugbọn ni gbati iyawo Ọpara lọ ti awọn ara ilu fi aake kọri lo pade rẹ ni inu ba bi NNDP nwọn na lẹ mọ Ọba, lọba fọga wọn joye
Olotu -Yẹyẹnatu o ba ọ ni?
Yẹyẹnatu : - Ẹ tun i i mi
Olotu - Ti a ba bere lọwọ ọba nkọ ?

Yẹyẹnatu - Ko gbọdọ sọ ohun to ṣelẹ. Bo ba sọ ọro gbe. Ko ni sọ fun yin pe lọjọ ti Akintọla ti ilẹkun ile ọlọpa Ilaro afojudi ati abuku Akintọla fi kan on, ko ni sọ fun yin pe nitori ki on ma ba a fi on oye ti on silẹ ni oa ṣe fi ọmọ Ọṣun jẹ oye idile Ilaro
Olotu Ẹwo ni iwọ nṣe gan
Yẹyẹnatu Ẹgbẹ majẹkobajẹ ni awa nṣe.
Olotu Nibo ni iyẹn wa ?
Yẹyẹnatu Kakiri ni ẹgbẹ ẹgbẹ lo si nṣe e ayafi ẹgbẹ ọlọwọ, egbe lomi ati egbe ọkọlin.
Olotu Nitori kini ?
Yẹyẹnatu Notoripe gbogbo awọn wọnyi ko si nibi kọ ma baje,
Olotu Ko le baje.
Yẹyẹnatu Lagbara Oluwa ko ni baje ṣugbọn ka ṣọra ka ma dibo fun NNA ko ma ba a je Ẹ DIBO FUN U P G A


**Kini E Nduro Fun ?**

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen) asọ oke, Tapẹta Sapẹti ati orişirişi asọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni iṣẹju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ

**JOYCE LAUNDRETTE SERVICE**

**34, Ojo — Oniyun Street,**
**Apapa Road Ebute Mẹtta.**

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A e wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi iṣẹ wa ti dara to owo pọọku ni a si ngba

EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

**TESSYDRE**

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti meji irufẹ rẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala losan tabi sun awọn iya wọn gbogbo Ogorun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ ṣugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessyd re rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu Agọnyin (CHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni wọn si nlọ fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wawa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osinu fẹkun fekun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişu, gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro afẹfẹfẹ ati orişirişi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu ni iba Ehin HIHU" gbogbo. Tessy dre a ma mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati Isan ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba ṣe amọdi rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọsẹ dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbaya wọn ti wọn jẹun dara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

**Bere Egbogi Ni Ṣọbu Awọn:—**

WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba

